


**Láti ọwọ́ Ààrẹ Henry B. Eyring**
Olùdámọ̀ràn Kínní nínú Àjọ Ààrẹ Ìkínní

# Ìmoore ní Ọjọ́ Ìsinmi

*Fún àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn, Ọjọ́ Ìsinmi jẹ́ ọjọ́ ìmoore àti ìfẹ́*

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin mi ọ̀wọ́n tí ẹ wà káàkiri àgbáyé nínú Ìjọ Jésù Krístì ti Àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn. Mo fi ìmoore hàn pé Ààrẹ Thomas S. Monson ti ní kí nsọ̀rọ̀ nínú ìpàdé àpapọ̀ ní ọjọ́ ìsinmi yí. Mo gbàdúrà pé kí Ẹ̀mí Mímọ́ gbé àwọn ọ̀rọ̀ mi lọ sínú ọkàn yín.

Ní òní mo ní ìfẹ́ láti sọ̀rọ̀ nípa ìmọ̀lára ti ọkàn. Ọ̀kan tí èmi ó dojúkọ ní òní ni ìmoore—nípàtàkì ní Ọjọ́ Ìsinmi.

A ní ìmọ̀lára ìmoore fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ nkan: inúrere láti ọ̀dọ̀ àlejò kan, oúnjẹ nígbàtí ebi npa wá, òrùlé lórí wa nígbàtí àwọn ìjì bá dìde, eegun rírún ti ó gba ìwòsàn, àti ẹkún ọkàn ti ọmọ titun. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ lára wa yíò rántí ìmọ̀lára ìmoore ní irú àsìkò náà.

Fún àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn, Ọjọ́ ìsinmi jẹ́ ọjọ́ ìmoore kan àti ìfẹ́. Olúwa kìlọ̀ fun àwọn Ènìyàn Mímọ́ ní Jackson County, Missouri, ní 1831 pé wọ́n gbọ́dọ̀ darí àdúrà wọn àti ìdúpẹ́ sí ọ̀run. Àwọn Ènìyàn Mímọ́ ìṣaájú ni a fun ní ìfihàn nípa bí wọn ṣe lè pa ọjọ́ Ìsinmi mọ́ àti bí wọn ṣe lè gbàwẹ̀ àti àdúrà.[1]

Àwọn, àti àwa, ni Olúwa sọ fún bi wọn ṣe lè jọ́sìn àti ṣe ọpẹ́ ní ọjọ́ Ìsinmi. Gẹ́gẹ́bí ẹ ṣe lè sọ, ohun to ṣe pàtàkì jùlọ ni bí a ṣe ní ìmọ̀ara sí nípa olùfúnni àwọn ẹ̀bùn náà. Níbí ni àwọn ọ̀rọ̀ ti Olúwa nípa bí a ṣe lè dúpẹ́ àti bí a ṣe lè ní ìfẹ́ lọ́jọ́ Ìsinmi:

"Mo fun wọn ní òfin kan, báyìí pé: Ìwọ yíò fẹ Olúwa Ọlọ́run rẹ pẹ̀lú gbogbo ọkàn rẹ, pẹ̀lú gbogbo agbára rẹ, inú rẹ, àti okun; àti pé ní orúkọ Jésù Kristì ni ìwọ ó máa sìn Ín. . . .

"Ìwọ yíò dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run rẹ nínú ohun gbogbo.

"Ìwọ yíò rú ẹbọ sí Olúwa Ọlọ́run rẹ nínú òdodo, àní níti irobìnújẹ ọkàn àti ẹ̀mí irẹ̀lẹ̀."[2]

Àti pé nígbánáà, Olúwa tún kìlọ̀ nípa ìkùnà láti ní ìfẹ́ àti láti mọ̀yì Bàbá Ọ̀run àti Jésù Krístì gẹ́gẹ́bí olùfúnni àwọn ẹ̀bùn: "Kò sí nínú ohunkóhun tí ènìyàn fi nṣẹ Ọlọ́run, tàbí tí ìnú Rẹ̀ ru sókè sí ẹnikẹ́ni, bíkòṣe àwọn wọnnì tí kọ̀ jẹ́wọ́ Rẹ̀ nínú ohun gbogbo, kí wọ́n sì gbọ́ran sí àwọn òfin rẹ̀."[3]

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ lára yín tí ó ngbọ́ tẹ́lẹ̀ ngbádùn Ọjọ́ Ìsinmi gẹ́gẹ́bí ọjọ́ láti rántí àti láti dúpẹ́ sí Ọlọ́run fún àwọn ìbùkún. Ẹ rántí orin tí ó mọ́ wa lára:

*Nígbàtí ìji ayé bá nyí yín káàkiri,*
*Nígbàtí ẹ sọ̀rètí nù, tí ẹ ro pé gbogbo rẹ̀ ti tán,*
*Ka ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìbùkún rẹ̀;*
*dárúkọ wọn ní ọ̀kọ̀ọ̀kan,*
*Yíó sì yà ọ́ lẹ́nu ohun tí Olúwa ti ṣe.*

*Ka Àwọn Ìbùkún Rẹ*
*Dárúkọ wọn ní ọ̀kọ̀ọ̀kan.*
*Ka Àwọn Ìbùkún Rẹ*
*Wo ohun ti Ọlọ́run ti ṣe. . . .*

*Ṣe o ní àjàgà pẹ̀lú ẹrù wúwo?*
*Njẹ́ ó dàbíi pé àgbélèbú tí a gbé rù ọ́ wúwo jù?*
*Ka àwọn ìbùkún rẹ; gbogbo iyèméjì yíò fò lọ,*
*Ìwọ yíò sì máa kọrin bí àwọn ọjọ́ ṣe nlọ.*[4]

Mò ngba àwọn lẹ́tà àti ìbẹ̀wò látọ̀dọ̀ àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn tí wọ́n ní ìmọ̀ara àjàgà pẹ̀lú ẹrù wúwo. Àwọn kan súnmọ́ níní èrò pé, ó kéréjù fún wọn, gbogbo rẹ ti tán. Mo nírètí mo sì gbàdúrà pé ohun tí èmi ó sọ yíò ṣe ìrànlọ́wọ́ láti mú kí iyèméjì fò lọ àti pé kí orin kíkọ bẹ̀rẹ̀ nínú ọkàn wa.

Ìbùkún àkọ́kọ́ fún èyí tí ẹ lè fi ìmoore hàn ni pé ẹ wà nínú ìpàdé oúnjẹ Olúwa náà rárá, ní kíkórajọ pẹ̀lú ọkan tàbí ju méji lọ lára àwọn ọmọẹ̀hìn Rẹ̀ ní orúkọ Rẹ̀. Àwọn kan wà nílé tí wọn kò lè dìde kúrò lorí ibùsùn wọn. Àwọn kan wà tí wọn yíò fẹ́ láti wà ní ibi tí ẹ wà ṣùgbọ́n dípò bẹ́ẹ̀ tí wọ́n nsìn ní ilé ìwòsàn tí wọ́n sì npèsè ààbò gbangba tàbí wọ́n ndá ààbò bò yín nínú ewu ti ẹ̀mí ara wọn ní àwọn aginjù kan tàbí igbó. Ní òtítọ́ pé ẹ lè kórajọ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé pẹ̀lú Ènìyàn Mímọ́ kan míràn, kí ẹ lè ṣalábápín oúnjẹ Olúwa ni gbogbo ohun tí ẹ nílò láti fi ìmoore hàn àti láti fẹ́ Ọlọ́run fún inúrere.

Nítorí ti Wòlíì Joseph Smith àti ìmúpadàbọ̀sípò ìhìnrere, ìbùkún kejì tí a lè kà ni pé a ní ànfàní láti jẹ oúnjẹ Olúwa ní ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀—múrasílẹ̀, bùkún, gbé e kiri nípa ọwọ́ àwọn ìránṣẹ́ Ọlọ́run tí a fún láṣẹ. A lè fi ìmoore hàn

nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bá fẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ fún yín pé àwọn ọ̀rọ̀ àdúrà oúnjẹ Olúwa, tí wọ́n fifún wa látẹnu àwọn olùdìmú oyèàlùfáà tí ó ní àṣẹ, ní ọ́wọ́ láti ọwọ́ Bàbá wa Ọ̀run.

Nínú gbogbo ìbùkún tí a lè kà, èyí tí ó ga jùlọ gidi ni ìmọ̀lára ìdáríjì tí ó nwá nínú ṣíṣe alábápín oúnjẹ Olúwa. A óò ní ìmọ̀ara ìfẹ́ gíga jùlọ àti ìmọnyì fún Olùgbàlà, enití ìrúbọ àìlópin rẹ̀ mú kí ó ṣeéṣe láti gba ìwẹ̀nùmọ́ ẹ̀ṣẹ̀. Bí a ṣe nṣe alábápín búrẹ́dì àti omi, à nrántí pé Ó jìyà fún wa. Àti pé à nfi ìmoore hàn fún ohun tí Ó ti ṣe fún wa, a ó ní ìmọ̀ara ìfẹ́ Rẹ̀ fún wa àti ìfẹ́ wa fun Un.

Ìbùkún ìfẹ́ tí à ngbà yíò mú kí ó rọrùn fún wa láti pa òfin kí a "rántí Rẹ̀ nígbàgbogbo mọ́."[5] Àní a lè ní ìmọ̀lára ìfẹ́ àti ìmoore, bí mo ti ṣe, sí Ẹ̀mí Mímọ́, èyí tí Bàbá Ọ̀run ṣèlérí pé yíò wà pẹ̀lú wa nígbàgbogbo bí a bá dúróṣinṣin lótítọ́ sí àwọn májẹ̀mú tí a ti ṣe. A lè ka gbogbo àwọn ìbùkún wọnnì ní ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ ki a si ní imọ̀lara imoore.

Ọjọ́ Ìsinmi jẹ́ ìgbà pípé kan láti rántí májẹ̀mú tí ẹ ṣe ninú omi ìrìbọmi láti sin àwọn ọmọ Bàbá Ọ̀run. Mímú ìlérí náà ṣẹ pẹ̀lú kíkópa nínú kíláàsì tàbí iyejú pẹ̀lú èrò ọkàn kíkún ní ọ̀nà lati gbé ìgbàgbọ́ duro ati ifẹ́ ni ààrín àwọn arákùnrin àti arábìnrin tí wọ́n wà níbẹ̀ pẹ̀lú wa. Ìlérí náà yíò pẹ̀lú fífi ìtújúká mú àwọn ìpè wa ṣẹ.

Mo fi ìmoore hàn fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọjọ́ ìsinmi tí mo kọ́ iyejú àwọn díákónì ní Bountiful, Utah, bákannáà ní kíláàsì Ilé Ìwé Ọjọ́ Ìsinmi ní Ìdaho. Àní pé mo rántí àwọn ìgbà ti mo sìn bí olùrànlọ́wọ́ sí ìyàwó mi nínú kíláàsì àwọn ọmọ ọwọ́, níbi tí kókó iṣẹ́ mi ti jẹ́ láti ṣà àti láti fun wọn ní ìṣeré.

Ó jẹ́ ọ̀pọ̀ ọdún kí ntó mọ̀ nípa Ẹ̀mí pé iṣẹ́ ìsìn mi jẹ́jẹ́ náà fún Olúwa dára nínú ayé àwọn ọmọ Ọlọ́run. Ó yàmí lẹ́nu pé, ọ̀pọ̀ lára wọn ti rántí gbígbésókè ìgbìdánwò mi láti sìn wọ́n fún Ọgá náà ní àwọn Ọjọ́ Ìsinmi wọnnì.

Gẹ̀gẹ̀bí a kò fi lè rí àwọn àbájáde ti iṣẹ́ ìsìn ara wa tí à nṣe ní ọjọ́ Ìsinmi nígbàkugbà, a le má lè rí akópọ̀ èrè ti àwọn ìránṣẹ́ ti Olúwa míràn. Ṣùgbọ́n Olúwa nti ìjọba Rẹ síwájú jẹ́jẹ́jẹ́ nípa àwọn ìránṣẹ́ Rẹ̀ olódodo àti onírẹ̀lẹ̀, pẹ̀lú ẹ̀fẹ̀ díẹ̀, lọ sí ọjọ́ ọ̀la ológo mìllẹ́níà. Ó gba ti Ẹ̀mí Mímọ́ láti rí ìwò dídára náà.

Mo dàgbà sókè ní lílọ sí ìpàdé oúnjẹ Olúwa ní ẹ̀ka kan ní New Jersey pẹ̀lú àwọn ọmọ ìjọ díẹ̀ nìkan àti ẹbí kan, ti ara mi. Ọdún marundinlọgọọrin sẹ́hìn, mo ṣe ìrìbọmi nínú ilé-ìjọsin kíkọ́ Ìjọ kanṣoṣo ní Pennsylẹania àti New Jersey. Ṣùgbọ́n níbi tí ẹ̀ka kékeré kan wà ní Princeton, New Jersey, Wọ́ọ̀dù nlá méjì ni ó wà nísisìnyí. Àti pé ní ọjọ́ díẹ̀ sẹ́hìn, ẹgbẹgbẹ̀rún àwọn ọ̀dọ́ ṣeré nínú ayẹyẹ tó ṣíwájú ìyàsímímọ́ ti Tẹ́mpìlì Philadephia Pennsylvania.

Gẹ́gẹ́bí ọ̀dọ́mọkùnrin kan, mo gba ìpè gẹ́gẹ́bí ìránṣẹ́ ìhìnrere ẹ̀kùn níbi tí a ti njọ́sìn ní ọjọọjọ́ Ìsinmi ní ilé ìjọsìn kanṣoṣo ní Albugbuergbue, New Mexico. Ní òní tẹ́mpìlì kan wà àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ eèkàn.

Mo kúrò ní Albugbuergbue láti lọ sí ilé ìwé ní Cambridge, Massachusetts. Ilé ìjọsìn kan àti ẹ̀kùn kan tí ó káàkiri ọ̀pọ̀ Island Massachusetts àti Rhode ni ó wà. Mo wakọ̀ lórí òkè dídára orílẹ̀ èdè náà lọ sí àwọn ìpàdé oúnjẹ Olúwa ní áwọn ẹ̀ka tíntín, púpọ̀ ní àwọn ohun èlò àyálò tàbí àwọn ilé àtunṣe. Nísisìnyí tẹ́mpìlì mímọ́ Ọlọ́run kan wà ní Belmont, Massachusetts, àti àwọn eèkàn tó tẹ́ káàkiri ẹ̀gbẹ́ orílẹ̀ èdè.

Ohun tí èmi kò rí dáadáa nígbànáà ni pé Olúwa ndà Ẹ̀mí Rẹ̀ jáde Sórí àwọn ènìyàn nínú àwọn ìpàdé oúnjẹ Olúwa wọnnì. Mo lè ní ìmọ̀ara rẹ̀, ṣùgbọ́n èmi kò lè rí bi ó ti tó àti ìgbà tí Olúwa lérò láti kọ́ àti láti gbé ògo ìjọba Rẹ̀ ga. Wòlíì kan, nípa ìfihàn, rí ó sì ṣe àkọsílẹ̀ ohun tí a lè rí fúnra wa. Nífáì sọ pe nọ́mbà wa àpapọ̀ ko l ga, ṣùgbọ́n pé àwọn àkópọ̀ ìmọ́lẹ̀ náà yíò jẹ́ ìran láti rí:

"Ó sì ṣe tí mo wo ìjọ ọ̀dọ́ àgùtàn Ọlọ́run, wọ́n sì kéré ni oye. . . .

Ó sì ṣe tí èmi, Nífáì, kíyèsí agbára Ọ̀dọ́-àgùtàn Ọlọ́run, tí ó sọ̀kalẹ̀ sórí àwọn ènìyàn mímọ́ ti ìjọ onígbàgbọ́ ti Ọ̀dọ́-àgùtàn, àti sórí àwọn ènìyàn májẹ̀mú ti Olúwa, àwọn tí a túká sórí gbogbo ojú àgbáyé; wọ́n sì gbáradì pẹ̀lú òdodo àti pẹ̀lú agbára Ọlọ́run nínú ògo nlá."[6]

Ní àsìkò yí, irú àpéjúwe ti àpóstélì kannáà nípa ipò wa àti àwọn ànfàní tó wà níwájú ní akọsílẹ̀ rẹ̀ wà nínú Ẹ̀kọ́ àti àwọn Májẹ̀mú.

"Ẹ kò ìítì ní òye síbẹ̀síbẹ̀ bí àwọn ìbùkún nlá tí Bàbá ní nínú ọwọ́ ara rẹ̀ ṣe tó tí ó sì ti múrasílẹ̀ fún yín;

"Ẹ kò lè gba gbogbo àwọn ohun wọ̀nyí mọ́ra nísisìnyí; bí ó tilẹ̀ rí bẹ́ẹ̀, ẹ túјúká, nítorí èmí ó darí yin lọ. Ìjọba náà jẹ́ tiyín àti pé àwọn ìbùkún èyí nì jẹ́ tiyín, àwọn ọ̀rọ̀ ayérayé jẹ́ tiyín.

"Ẹni tí ó bá gba gbogbo ohùnkan pẹ̀lú *ṣíṣọpẹ́* yíò di ológo; àti pé ohun ti ayé yí gbogbo ni a ó fikún yín, àní ọgọ́ọ̀rún agbo, bẹ́ẹ̀ni, jùbẹ́ẹ̀."[7]

Mo ti ní ìmọ̀ara pé ìyípadà ti dídàgbà ìmoore fún àwọn ìbùkún àti ìfẹ́ Ọlọ́run tó npọ̀si káàkiri Ìjọ. Ó dàbíí mímú àwọn ìgbà àti ibití àwọn àdánwò ìgbàgbọ́ àwọn ọmọ Ìjọ ti nyára si, níbití wọ́n ti nbẹ̀bẹ̀ sí Ọlọ́run fún irànlọ́wọ́ láti tẹ̀síwájú.

Àwọn ìgbà tí a bá nlọ nínú rẹ̀ ní àwọn àdánwò tó lè bí wọ́n ti ṣe fún àwọn ènìyàn Álmà lábẹ́ ìkà Ámúlónì, tí o gbé àjàgà tí ó wúwo jùlọ fún wọn láti gbé:

Ó sì ṣe tí ohùn Olúwa tọ̀ nwọ́n wá nínú ìpọ́njú nwọn, tí ó wípé: Ẹ gbé orí i yín sókè, kí ẹ sì túјúká, nítorítí èmi mọ májẹ̀mú tí ẹ̀yin ti dá pẹ̀lú mi; èmi yíò sì dá májẹ̀mú pẹ̀lú àwọn ènìyàn mi, èmi yíò sì gbà nwọ́n kúrò nínú oko-ẹrú.

Èmi yíò sì dẹ ìnilára tí a gbé lée yín ní éjìká, ptíé ẹ̀yin kò lè mọ̀ ọ́ lórí ẹ̀hìn nyín, bí ẹ̀yin tilẹ̀ wà nínú oko-ẹrú; èyí yíi ni èmi yíò ṣe kí ẹ̀yin kí ó lè dúró gẹ́gẹ́bí ẹlẹ́rí fún mi ní ọjọ́ tí nbọ̀, àti kí ẹ̀yin kí ó lè mọ̀ dájúdájú pé èmi, Olúwa Ọlọ́run nbẹ àwọn ènìyàn mi wò nínú ìpọ́njú nwọn.

Àti pénísisìyí ó ṣì ṣe tí ìnira tí a gbé ru Álmà àti àwọn arákùnrin rẹ̀ di fífúyẹ́; bẹ̀ni, Olúwa fún nwọn ní okun kí nwọ́n lè gbé ẹrù nã pẹ̀lú ìrọ̀rùn, nwọ́n si jọ̀wọ́ ara wọn silẹ̀ fun ifẹ́ Olúwa pẹ̀lú ọ̀yàyà àti sũrù."[8]

Ẹ̀yin àti èmi jẹ́ ẹlẹ́ẹ̀rí pé nígbàkugbà tí a bá pa àwọn òfin Olúwa mọ́, pàtàkì nígbàtí iyẹn le, Ó ti gbọ́ àdúrà

ọpẹ́ wa fún ohun tí Ó ti ṣe fún wa tí Ó ti gbọ́ àdúrà wa fún okun láti nífaradà nítoótọ́. Ju ìgbàkan lọ Ó ti mú wa túјúká bákannáà Ó mú wa ní agbára.

Ẹ lè tilẹ̀ máa ro ohun tí ẹ lè ṣe láti gbé ìgbé ayé ìjọsìn ní Ọjọ́ Ìsinmi yí gan an láti ṣàpèjúwe ímoore àti láti mú ara yín lókun àti àwọn ẹlòmíràn fún àwọn àdánwò to wá níwájú.

Ẹ lè bẹ̀rẹ̀ lóní pẹ̀lú àdúrà ọpẹ́ ti araẹni àti ẹbí fun gbogbo ohun tí Ọlọ́run ti ṣe fún un yín. Ẹ lè gbàdúrà láti mọ ohun tí Olúwa yíò fẹ́ kí ẹ ṣe láti sìn Ín àti àwọn ẹlòmíràn. Pàápàá, ẹ lè gbàdúrà láti ní Ẹ̀mí Mímọ́ láti sọ nipa ẹnìkan fún un yín tí ó nìkanwà tàbí tí ó nílò ọ̀dọ̀ ẹnitˊi Olúwa yíò fẹ́ kí ẹ lọ.

Mo lè ṣèlérí fún un yín pé àdúrà yín a gbà, àti pé bí ẹ ṣe nṣiṣẹ́ lórí àwọn ìdáhùn ẹ ó rí gbà, ẹ ó rí ayọ̀ nínú Ọjọ́ Ìsinmi, ọkàn yín yíò kún àkúnwọ́ sílẹ̀ pẹ̀lú ìṣọpẹ́.

Mo jẹ́ ẹ̀rí pé Ọlọ́run Bàbá mọ̀ Ó sì fẹ́ràn yín. Olúwa Jésù Krísti, ṣètùtù fuń ẹ̀ṣẹ̀ yín nínú ifẹ́ fún un yín. Àwọ́n, Bàbá àti Ọmọ, mọ orúkọ yín bí Wọ́n ṣe mọ orúkọ Wòlíì Joseph Smith nígbàtí Wọn yọ síi. Mo jẹ́ ẹ̀rí pé èyí ni Ìjọ ti Jésù Krístì àti pé Òun yíò bu ọlá fún àwọn májẹ̀mú tí ẹ ti ṣe tí ẹ sì ntúnṣe pẹ̀lú Ọlọ́run. Ìwà ẹ̀dá yín gangan yíò yí padà láti dàbí Olùgbàlà si. Ẹ ó ní ìgbáradì ní àtakò sí àdánwò àti àtakò sí ìmọ́ara iyèméjì nipa òtítọ́. Ẹ̀yin yíò rí ayọ̀ nínú Ọjọ́ Ìsinmi. Mo sì ṣe bẹ́ẹ̀ ní orúkọ Jésù Krístì, àmín.

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁŃPẸ́**


1. Wo Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 59.
2. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 59:5, 7–8.
3. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 59:21.
4. "Ka àwọn Ìbùkún Rẹ," *Àwọn Orin* no. 241.
5. Mórónì 4:3; 5:2; Ẹ̀kọ́ àti àwọn Májẹ̀mú 20:77, 79.
6. 1 Nephi 14:12, 14.
7. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 78:17–19; àfikún àtẹnumọ́.
8. Mòsíàh 24:13–15.

## Àwọn Ìkọ́ni fún Ìgbà Tiwa

Láti oṣù kọkànlá ọdún 2015 sí oṣù kẹrin ọdún 2016 àwọn ẹkọ ti Oyè àlùfáà Mẹlkisédékì àti Ẹgbẹ Ìrànlọwọ ní ọjọ ìsinmi kẹrin ni a niláti múra rẹ sílẹ láti inú ìkan tàbí jùbẹẹ lọ lára àwọn ọ̀rọ̀ tí a fi fúnni ní ìpàdé gbogbogbòò ti oṣù kẹwàá ọdún 2015 Ní oṣù kẹwá ọdún 2016 a lè yan àwọn ọrọ bóyá láti inú ìpàdé àpapọ̀ gbogbogbò oṣù kẹrin tàbí oṣù kẹwá ọdún 2016 ÀwọnÀàrẹEèkànàtiẸkùngbọ́ dọ̀yanàwọnọ̀rọ̀èyítíwọnyíòlòníagbègbèwọn,tàbíwọnlègbéojúṣeyíléàwọnBíṣọọpù àtiàwọnààrẹẹkalọwọ

Àwọn ọrọ náà wà ní onírũrú èdè ní **conference.lds.org**.

© 2016 by Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹẹ ní USA Àṣẹ Gẹẹsì: 6/16. Àṣẹ Àyípadà èdè: 6/16. Ìyírọ̀padà ti *First Presidency Message, November 2016*. Yoruba. 12871 779



Láti ọwọ Ààrẹ Thomas S. Monson

# Ipa Ọ̀nà Pípé sí Ìdùnnú

*Mo jẹ́ ẹ̀rí nípa ẹ̀bùn nlá èyí tí ó jẹ́ ètò Bàbá wa fún wa. Ó jẹ́ ọ̀nà pipe kan sí àláfíà àti ìdùnnú.*

Ẹ̀yin olólùfẹ́ arákùnrin àti arábìnrin mi, méjèèjì níbí nínú Gbàgede Ìpàdé Àpapọ̀ àti káàkiri àgbáyé, bí ìmoore mi ṣe pọ̀ tó fún ànfàní láti ṣe àbápín àwọn èrò mi pẹ̀lú yín ní ààrọ̀ yí.

Ní àádọ́ta ọdún ó lé méjì sẹ́hìn, ní oṣù kéje 1964, mo ní iṣẹ́ láti ṣe ní Ìlú Nlá New York ní ìgbà tí wọn ṣe Ìtajà Àgbáyé níbẹ̀. Ní kùtùkùtù ààrọ̀ kan mo bẹ Ìṣíjà Mọ́rmọ́nì wò níbi ìtajà náà. Mo dé bẹ̀ ṣíwájú kí wọ́n tó fi eré ti Ìjọ hàn *Ìwákiri Ènìyàn Fún Ìdùnnú,* ìfihàn kan nípa ètò ìgbàlà èyí tí ó ti di ṣíṣètò Ìjọ kan. Mo joko tẹ̀lé ọ̀dọ́mọkùnrin kan bóyá ti ọjọ́ orí rẹ̀ máa jẹ́ marunlelọ́gbọ̀n. A sọ̀rọ̀ ránpẹ́. Kìí ṣe ọmọ ìjọ wa. Nígbànáà iná séjú, wọn sì bẹ̀rẹ̀ eré.

A fi etí sílẹ̀ sí ohùn arohìn bí ó ti ngbé ìbèèrè dídunni àti ti gbogbo ènìyàn jáde: "Níbo ni mo ti wá? Kíni ìdí tí mo fi wà níbí? Níbo ni mò nlọ nígbà tí mo bá kúrò ní ayé yí? Gbogbo ẹtí nàró láti gbọ́ ìdáhùn, àti pé gbogbo ojú wà lórí àfihàn àwòrán. Ìjúwe kan nípa ìṣíwájú ayé ní wọn fúnni, lẹ́gbẹ́ rẹ̀ pẹ̀lú àlàyé ti èrò ilẹ̀ ayé. A rí àwòrán tó wọnilọ́kàn nípa lílọ kúrò ní ayé yí ti bàbánlá tó dàgbà àti ìpadàrẹ́pọ̀ ológo rẹ̀ pẹ̀lú àwọn olùfẹ́ rẹ̀ tí wọ́n ti ṣíwájú rẹ̀ lọ sí ayé ẹ̀mí.

Ní ìparí ìfihàn tó dára nipa ètò Bàbá wa Ọ̀run yí fún wa, àwọn èrò tò jáde lọ́wọ̀ọ̀wọ́, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni ọ̀rọ̀ ìtàn náà wọ̀ lọ́kàn. Ọ̀dọ́mọkùnrin àlejò to tẹ̀lé mi náà kò dìde. Mo bèèrè boyá ó gbádùn eré náà. Ìdáhùn àtẹnumọ́ rẹ̀ ni pé: "Òtítọ́ ni èyí"

Ètò Bàbá wa fún ìdùnnú àti ìgbàlà wa ni àwọn ìránṣẹ́ ìhìnrere wa nṣe àbápín káàkiri àgbáyé. Kìí ṣe gbogbo ẹnití ó gbọ́ ọ̀rọ̀ ti ẹ̀mí yí ni ó ngbàá tí wọ́n sì ngbàá mọ́ra. Ṣùgbọ́n, àwọn ọkùnrin àti obìnrin nibi gbogbo, bíti ọ̀rẹ́ mi kékeré níbi Ìtàjà Àgbáyé ti New York, mọ òtítọ́ rẹ̀, wọ́n sì ngbé ẹsẹ̀ wọn sí ipá ọ̀nà tí yíò darí wọn lọ sílé láiléwu. Ìgbé ayé wọn á sì yípadà títíláé.

Kókó sí ètò náà ni Olùgbàlà wa, Jésù Krístì. Láìsí ètùtù ìrúbọ Rẹ̀, gbogbo ohun yíò sọnù. Kò tó, bákannáà, lásán, láti gbà Á gbọ́ àti iṣẹ́ ìránṣẹ́ Rẹ̀. A nílò láti ṣiṣẹ́ àti láti kọ́ ẹ̀kọ́, ṣe ìwákiri kí a sì gbàdúrà, ronúpìwàdà kí a sì ṣàtúnṣe si. A nílò láti mọ àwọn àṣẹ Ọlọ́run kía a sì pa wọ́n mọ́. A nílò láti gba àwọn ìlànà ìgbàlà Rẹ̀. Ní ṣíṣe èyí nìkan ni a lè gba, ìdùnnú ayérayé òtítọ́.

A jẹ́ alábùkún láti *ní* òtítọ́ náà. A ní àṣẹ láti *ṣe àbápín* òtítọ́ náà. Ẹ jẹ́ kí a *gbé ìgbé ayé* òtítọ́ náà, kí a lè kun ojú òṣùwọ̀n fún gbogbo ohun tí bàbá ní fún wa. Kìí ṣe ohunkan bíkòṣepe ó jẹ́ fún èrè wa. Àti pé nítorí, bí Ó ṣe sọ nípa ti Ara Rẹ̀, Èyí ni iṣẹ́ mi àti ògo mi—láti mú àìkú àti ìyè ayérayé ènìyàn wá sí ìmúṣẹ.[1]

Láti ìsàlẹ̀ inú ọkàn mi wá, àti gbogbo ìrẹ̀lẹ̀, mo jẹ́ ẹ̀rí nípa ẹ̀bùn nlá èyí tí ó jẹ́ ètò ti Bàbá fún wa. O jẹ́ ọ̀nà pípé kan sí àláfíà àti ìdùnnú méjèèjì níbí àti ní ayé tó nbọ̀.

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin mi, mo fi ìfẹ́ mi sílẹ̀ pẹ̀lú yín àti ìbùkún mi bi mo ṣe parí, mo sì ṣe bẹ́ẹ̀ ní orúkọ Olùgbàlà àti Olùràpadà wa, àní Jésù Krístì, àmín.

**ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Mósè1:39

© 2016 by Intellectual Reserve, Inc.All rights reserved. A tẹ ní USA Àṣẹ Gẹẹsì: 6/16. Àṣẹ Àyípadà èdè: 6/16. Àyípadà Èdè ti *Visiting Teaching Message, November 2016.* Yoruba. 12871 779